# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Karun : Osu Kini Ojo Kokandinlogbon, 2017**

**Akori oro: Aisododo**……Apa kini

**Eko kika: Romu 1: 18-32**

## Aisododo

Aisododo je gbogbo iwa ti ki se iwa-ododo tabi iwa-otito. Eyi je gbogbo iwa ese ati iwa buburu. A tun le se apejuwe re gegebi iwa-ibi ati iwa ti kobojumu. Nitorina, gbogbo iwa-odaran ni o je aisododo.

Aisododo ko duro lori awon iwa nikan, sugbon o wa ninu awon ofin pelu. Gbogbo ofin-aninilara ati ofin ti o nmu enia sin asinpa je ofin-aisododo.

Ofinkofin ti o ba nfi owo-ola gbani-loju, ti o si nfi eto enia dun u, pataki-julo awon ofin ti ko se-dede ati awon ofin ti nre mekunnu je; ni ofin aisododo.

## Iyonu Eda-enia

Aisododo je okan ninu awon ona ti awa eda-enia fi hun re ara wa je, ti a fi hun ni ara wa lara, ti a si nmu enia sin asinpa. Iwa yi je 'gbaju-gbaja' larin awa omo-adari-hurun, o si je ohun ti nyo gbogbo eya, t'okunrin t'obinrin ati gbogbo orile-ede ni abe orun l'enu.

Aisododo yi dabi aisan ti o ma nran, ti o si nran lati odo enikan si ekeji ni aijafara. Aisododo dabi aisan-jejere ti o ti kari gbogbo eya ago-ara enia. A tun le fi aisododo we ina-ajoopa ti o njo pelu agbara-nla ti o 'ndun-koko' mo iwa-laaye awa eda-enia.

Ni ode oni, aisododo yi je ohun ti o gbile larin awon enia ti ao daruko:

- Egbon ati aburo; Obi ati awon omo won; Oko ati aya; Larin ebi tabi iyekan
- Larin awon ore; Larin awon osise; Larin awon aladugbo; ati ninu ijo Olorun.

Eyi je ohun ti o ma nsele-julo larin ijoba ilu tabi ijoba orile-ede ati awon ara-ilu, o si tun ma nsele larin awon oga ile-ise ati awon omo-ise won.

Ibajepe ko si aisododo ile aiye yi iba ni ewa ati alafia gidigidi, ti yio si je ibi irorun ati ayo lati ma gbe, yato si 'gbonmisi- omi-oto' ti nsele lowolowo.

**Ko si aisododo ninu Olorun**

Olorun Olodumare je olododo, ko si si aisododo ninu re. O fi otito ati ododo se ipinle ite re ninu orun, nitorina ni o se lodi si gbogbo iwa aisododo.

**Aisododo eda-enia:** A kowe re wipe, Oluwa se akiyesi pe iwa buburu enia di pupo li aiye, O si ri wipe ero-okan enia ati ise enia je ibi patapata. Oluwa ri wipe ero-ngba ati ipinnu okan enia je ibi ni gbogbo igba. Inu Oluwa si baje nitori ti o da enia si aiye, o si dun u de okan re **Genesisi 6: 5-6**. Awon eda to'ku ti Olorun da, ko ba a ninu je, bikose awa eda-enia ti o ni'fe ti o si da ni aworan ara re.

**Noa se olododo:** Lowolowo ninu aiye, olododo enia sowon lati ri, sugbon alaisododo enia kun ibigbogbo. Bakanna ni o se sele ni igba Noa, nitoripe Oluwa so pe, Noa nikan ni olododo ninu iran na **Genesisi 7: 1**. Se o ti setan lati bo aisododo re sile, ki o ba le je okan lara awon olododo enia ninu iran yi?.

**Majemu Olorun:** Lotito ni Olorun da majemu pelu awa eda ti o da, wipe "Emi ki yio tun fi ile re nitori enia mo; beli emi ki yio tun kolu ohun alaaye gbogbo mo bi mo ti se" sugbon eyi ko tumo si wipe alaisododo enia ko ni jiya tabi yio lo ni aijiya **Genesisi 8: 21-22**. Yipada loni, ki o si ju iwa aisododo sile, ki idajo Olorun to wa si ori re.

**Ododo Olorun:** Olorun wa ki se ojusaju enia, kosi si aisedede tabi yiyi ejo-po lodo re. Torina, enia gbodo fi owo-soya wipe ko si aisododo ninu Olorun **Romu 9: 14**.
Niwon igbati Olorun je olododo, aisododo awa eda-enia ni o ngbe ori'yin fun Olorun ti o si njeri wipe olododo ni Olorun. Awon ese wa duro fun idi kan, nitoripe o se iranlowo fun awon enia lati ri bi ododo Olorun wa ti tobi to. Se ko wa ni dabi aisedede bi Olorun ko ba je wa niya nitori aisododo? **Romu 3: 5**. Nigbati o ti mo wipe iwo yio jiya awon ese re, ko gbogbo iwa aisododo sile.

**Polongo pe olododo ni Olorun:** O je ojuse gbogbo onigbagbo lati polongo ninu ipokipo ti won wa wipe Olorun je eni-idurosinsin, olotito ati olododo. Ninu awon onigbagbo, awon kan ma nfi were pe Olorun ni ejo, ti awon omiran si ma nbu Olorun nitori ipo ti won wa. Iru awon enia wonyi gbodo dekun iwa-ibi yi

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Orin Dafidi 92: 15**. Mase ba Eleda re ja tabi ba a wi'jo, sugbon polongo ododo re fun gbogbo eniti ngbe ninu aiye.

## Ipinnu Olorun

Olorun ni ipinnu ti o re'wa fun awa eda-enia, sugbon iwa ese wa ni o nse akoba fun ipinnu rere yi. Gbogbo enia ti o duro ni ona otito lai-yese, ti won si yera fun aisododo ni ipinnu yi yio wa si imuse fun.

**Olorun yio sanu fun aisododo wa:** Olorun ninu opolopo anu re yio darijin gbogbo asise wa, yio si fi oju fo aisedede wa, besini ko ni ranti awon ese wa mo. Olorun yio fi anu pa ese wa re, ko si ni ranti gbogbo iwa aisododo wa mo. Bibeli wipe "Emi o sanu fun aisododo won, ati ese won ati aisedede won ni emi ki yio ranti mo" **Heberu 8: 12**.

**Olorun gbegile iwe ofin ti a ko lodi:** Iso're Jesu Kristi Oluwa ni o mu ki o gbegile iwe ofin ti a ko lodi si wa, o mu kuro l'ona, o si kan mo agbelebu. Niwon igbati a ti ko wipe "O ti pa iwe majemu ni re, ti o lodi si wa: on li o si ti mu kuro loju ona, o si kan a mo agbelebu" **kolosse 2: 14**. Mase pada si idi eebi re mo, sugbon bere sini rin li otun iwa, ki o si ma sin Olorun li otun emi.

**Olorun nbe larin wa:** Oluwa nbe larin wa lati to wa si ona ati lati da abo bowa. O ti so wipe "Emi ki yio fi o sile, beni emi ki yio ko o". Oluwa yio se dede pelu re, beli ki yio se buburu. Ni ojojumo ni o nmu idajo re wa si imole, ki itase; sugbon awon alaisoto ko mo itiju **Sefaniah 3: 5**. Niwon igbati e ba ti fi iberu Oluwa kun aiye yin, ti e si gba Oluwa ni kikun, yio ma farahan larin yin lati to ipase yin.

**Awon olufokansin yio ma gbe lai'lewu:** Awon olufokansin ti ko da'le igbagbo won, ki yio wu iwa aisododo, beni won ki yio pa iro tabi se etan pelu ara won. Won yio ma gbe ni ailewu, enikan ki yio si deruba won **Sefaniah 3: 13**. Ki ore-ofe Oluwa yi to wa si imuse ninu aiye re, o ni lati ko esu ati ese sile.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kefa: Osu Keji Ojo karun, 2017**

**Akori oro: Aisododo** – Apa Keji

**Eko kika: Romu 1: 18-32**

Ao tesiwaju ninu eko yi nipa oniruru awon iwa aisododo.

**Awon iwa aisododo**

Opolopo awon iwa eda-enia ni a ka gegebi aisododo ninu Bibeli ati ni iwaju Olorun. Die ninu re ni ao soro nipa won lati fi si i awon onigbagbo ni'ye, ki won ma ba bo sinu awon panpe esu.

**Kikan Kristi mo agbelebu ni ekeji:** Opo kristiani ni won nkan Jesu Kristi Oluwa mo agbelebu ni ojojumo nipa iwakiwa won. Iru awon enia yi ti won ti fi enu won jewo Jesu Kristi ni Oluwa ati Olugbala won, nwon tun nse Omo Olorun nipa ise won. Iwe mimo so wipe awon ti a ti la loju lekan, ti nwon si ti to ebun orun wo, ti nwon si ti di alabapin Emi Mimo; ti nwon si ti to oro rere Olorun wo, ati agbara aiye ti nbo; ti nwon si ti subu kuro, ko le se ise lati so won di otun si ironupiwada, nitori nwon tun kan Omo Olorun mo agbelebu si ara won ni otun, nwon si dojuti i ni gbangba **Heberu 6: 4-6**. Sora, mase jeki awon iwa aisododo re tun kan Jesu Kristi mo agbelebu ni ekeji, ki o si dojuti i ni gbangba. Nibikibi ti o ba wa, ati ninu ohun gbogbo ti o ba nse, o ko gbodo fi aye sile ki oruko Olorun ti o li ogo di isoro-odi si lati ipase re **Romu 2: 24**.

**Wiwa ogo ti ara-eni:** Opolopo kristiani ni ode-oni ni won nwa ogo ara tiwon; Ohun ti o je won logun ni okiki, ipo, iyi ati ola ti ao fi fun won ni oju awon enia. Iwa wiwa ogo ara-eni yi je ohun ti o lodi si eko Bibeli Mimo. O je ohun ti o gbile larin awon kristiani lati so wipe "Emi yio wo o san kuro ninu ailera re tabi loni ti o ti fi oju kan mi Emi yio gba o lowo awon isoro re" Irufe awon enia wonyi gbodo mo wipe ohunkohun ti o ba sele, "ki ise nipa ipa tabi agbara won, bikose nipa ore-ofe Olorun". Iwe Orin Dafidi wipe awa eda-enia ko gbodo fi ogo fun ara wa, bikose ki a ma fi ogo fun Olorun nigba gbogbo, ki a si ma yin ninu ohun gbogbo. "Ki ise fun wa, Oluwa, ki ise fun wa, bikose oruko re ni a fi ogo fun nitori anu re, ati nitori otito re **Orin Dafidi 115: 1**. Nitorina, bi enyin ba nje, tabi bi enyin ba nmu, tabi ohunkohun ti enyin ba nse , e ma se gbogbo won fun ogo Olorun **1 Korinti 10: 31**. Si'wo gbogbo iwa wiwa ogo ara-eni, nitoripe enikeni ti

o nwa ogo ara tire ko gba otito gbo, bikose aisododo; iru awon enia wonyi yio si je iya, nitoriti won ti mu Olorun binu **Romu 2: 8**. Bi o ko ba fe irunu ati ibinu Olorun ninu aiye re, dekun gbogbo akitiyan wiwa ogo ara tire, ki o si fi ogo fun Olorun ni kikun. Bi o ko ba fe ki rudurudu ati ibi ki o gba isakoso aiye re, fi opin si awon iwa wiwa ogo ara-eni loni **Jakobu 3: 16**.

**Mase yan ore nipase mammoni aisoto:** Enikeni ti o nfe lati je ore re tabi ni ajosepo pelu re gbodo je olotito ati olododo. Gbogbo ibasepo re ko gbodo je lori iro, etan tabi awon ohun asan aiye yi **Luku 16: 9-11**.

**Idajo aisoto ati ojusaju:** Mase se idajo aisoto tabi se ojusaju awon enia buburu; Mase gbe ebi fun alare tabi gbe are fun elebi; mase fi iya je alaise, ki o si da odaran sile **Orin Dafidi 82: 2**. Iwo ko gbodo se aisododo ni idajo: iwo ko gbodo gbe talaka, beni iwo ko gbodo se ojusaju alagbara: li ododo ni ki iwo ki o ma se idajo enikeji re **Lefitiku 19: 15**. Wu iwa bakanna si gbogbo enia; se idajo li ododo, ni alaije-wipe titori ipo won ninu awujo tabi ola won.

**Titan ihin eke kakiri:** Iwo ko gbodo tan ihin eke kakiri larin awon enia. Iwo ko gbodo tan gboyi-soyi tabi iro kale, lati da ile awon enia ru tabi lati tu ijo Olorun. Iwo ko gbodo je olofofo, tabi asoro-eni-lehin, tabi afi-oro-kele-ba-tenije, nitori ere. Gbogbo awon iwa ti a ti daruko yi je aisododo, eyiti o le mu ki oju Olorun koro si enia. A kowe re wipe "Iwo ko gbodo gba ihin eke: mase li owo si i pelu enia buburu lati se eleri aisododo" **Eksodu 23: 1**. Nitorina, mase tan ihin iro kale; mase fi owosowopo pelu enia buburu lati pa iro ni ile-ejo tabi se iranlowo fun eniti o jebi, nipa jije eleri aisododo.

**Ireje ati jibiti:** A ni lati mo wipe Olorun yio gbesan lara enikeni ti o nfi owo-ola gba  arakunrin tabi arabinrin ninu Oluwa loju. Torina, mase re enikeni je ninu ohunkohun, nitoripe oju Oluwa nwo o. Yio si san esan gbogbo ise re **1 Tessalonika 4: 6**. Ireje ati jibiti je awon iwa aisododo ti o ni lati yera fun ni gbogbo igba.

**Inilara ati tite talaka m'ole:** Ase Oluwa ni wipe, a ko gbodo ni ara wa lara, sugbon o ni irufe awon enia kan, ti Olorun yio ro'jo idajo le ori awon aninilara won ni kiakia. Bibeli wipe "mase ni opo lara, tabi alaini-baba, alejo tabi talaka; ki enikeni ninu nyin ki o mase gbero ibi li okan si arakunrin re" **Sekariah 7: 10, Deuteronomi 24: 14-17**. Ninu aiye loni, awon enia hun ni talaka lara, lati ko oro jo. Awon olowo ati awon oselu npin oro orile-ede larin ara won, ni aibikita fun awon talaka; won ti gbagbe wipe awon yio di alaini nikehin aiye nwon. "eniti o

nni talaka lara lati mu oro po, ti o si nta oloro lore, yio di alaini bi o ti wu ki o se" **Owe 22: 16**. Gbogbo okan ti won parapo ninu ijo-Olorun, tabi ile-ise, tabi ninu ijoba orile-ede ti won nte talaka mole nipase oniruru ofin ati owo-ori; ki yio ni anfani lati gbadun oro ti won kojo, besini won koni ni ore-ofe ati na owo ti won kojo ni ona-eru ni Oluwa wi **Amosi 5: 11**. Olorun, ranti ileri re, wipe Iwo yio dide nitori inira awon talaka ati nitori imi-edun awon alaini; Iwo yio yo won si ibi ailewu kuro lowo awon eniti nfe si won, besini Iwo yio fi Igbala ti okan won npongbe fun won **Orin Dafidi 12: 5**. Dide loni Oluwa gegebi oro re, nitori iponju awon alailera ati omije awon talaka, gba wa la gegebi ongbe okan wa, ki o si da abo bowa lowo awon ti o nro ibi ro wa.

**Owo ele ati ere aisoto:** Owo-ele je aisododo ti o gbile larin awa enia. Nigbakugba ti enia ba gba owo-ele ti o papoju lori gbese ti won ya ara ninu Oluwa, ohun ti won ma nwi ni wipe "iye owo lagbara pupo (cost of money is very high)". Igbese yi lodi si eko Bibeli, toripe ase Oluwa ni wipe a ko gbodo gba owo-ele tabi eda lowo awon ara ninu Oluwa **Lefitiku 25: 36-37**. Lowolowo kise owo-ele nikan ni o gbile bikose eda ati ere-aisoto gbile lapoju larin araiye. Enikeni ti o fi ele ati ere aisoto so oro re di pupo, o ko o jo fun eniti yio sanu fun awon talaka **Owe 28: 8**. Ere ti o ba ti ipase owo-ele wa yio kangun si apo awon ti yio sanu fun awon talaka.

**Mase yi ejo po:** Iwo ko gbodo yi idajo-otito kuro lodo awon talaka ninu oran won. Enikeni ti o ba se e awon enia ni idajo-otito toripe won nse talaka je alaisododo enia. Nitorina, ri wipe awon talaka ri idajo ogbo-gba gba ni ile ejo, gegebi a ti kowe re pe "iwo ko gbodo yi ejo talaka po li oran re" **Eksodu 23: 6**. Se bakanna fun talaka ati olowo ninu gbogbo ejo won.

**Mase gba abetele lati yi idajo po:** Enikeni ti o ba gba abetele lati pa alaise tabi lati se idajo aisoto si talaka eni egun ni. Egun ni fun eniti o gba ore tabi abetele lati pa alaise **Deuteronomi 27: 25**. Olorun se ikilo wipe, gbigba abetele yio muki enia fi oju fo awon asise, toripe abetele ni nmu ki olododo enia yi otito po. Mase gba ore-abetele: nitori abetele ni ifo awon ti o riran loju, a si yi oran awon olododo po **Eksodu 23: 8**. Ri daju pe o ko gba abetele tabi fun enia ni abetele, ki o maba ba ara re ni ipo ti o nira. Fun idi eyi ni iwe mimo se wipe, "iwo ko gbodo lo idajo; iwo ko gbodo se ojusaju enia: beni iwo ko gbodo gba ebun; nitoripe ebun ni ifo ologbon ni oju, on a si yi oro olododo po" **Deuteronomi 16: 19**. Se dogba-ndogba, mase se ojusaju; ri daju pe o ko si i ofin tumo tabi si i idajo se.

**<u>Isedede ati idogba:</u>** Mase se aidogba si enia, sugbon se dogba-ndogba pelu gbogbo enia. Sa fun aidogba, niwon igbati o je okan lara awon iwa aisododo. Se idajo ododo fun awon osise tabi omo-lehin re, fi eti sile si edun-okan won, ki o si yanju re gegebi ipa tabi agbara ti Olorun fifun o **<u>Jobu 31: 13</u>**. Jeki dede ati dogba-ndogba je akomona re.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

### Ose Keje : Osu Kini Ojo Kokandinlogbon, 2017

**Akori oro: Aisododo**……Apa keta

**Eko kika: Romu 1: 18-32**

Ao tesiwaju ninu eko yi, nigbati ao soro nipa aisododo larin awon orile-ede agbaiye.

**<u>Aisododo larin awon orile-ede</u>**

Bibeli wipe "… aiye o si di ogbo bi ewu, awon ti ngbe inu re yio si ku bakanna: sugbon igbala mi o wa titi lai, ododo mi ki yio si pare" **<u>Isaiah 51: 6</u>**. Niwon igbati aiye ti ndi ogbo lo pelu awon olugbe inu re, nje ko yeki eda-enia kun fun ogbon; ki won sunmo Eleda won, dipo eyiti won fi ni ife ejo lailai ni, eniti a npe ni Esu ati Satani. Bi aiye ba ngbo bi aso, etise, ti iran-enia ko fi mo wipe igba kukuru ni won ni, ki won si wa igbala aiyeraye Olorun ati ododo re ti ki yio dekun?

**<u>Alaimore ati alaibowo fun Olorun:</u>** Lowolowo ninu aiye akainiye orile-ede ni won mo Olorun, sugbon won ko bowo fun, won ko si yin i logo bi Olorun; beni won ko si dupe gbogbo ore ti o ti se fun won: sugbon won wa idasan won, a si mu okan omugo won sokunkun. Won npe ara won ni ologbon sugbon won di asiwere. Won si pa ogo Olorun ti ki idibaje da, si aworan ere enia ti idibaje, ati ti eiye, ati ti eranko elese merin, ati ohun ti nrako **<u>Romu 1: 21-23</u>**. Won ti gbagbe ofin Olorun ti o wipe "Iwo ko gbodo ya ere fun ara re, tabi aworan ohun kan ti mbe loke orun, tabi ti ohun kan ti mbe ni isale ile, tabi ti ohun kan ti mbe ninu omi ni isale ile" **<u>Eksodu 20: 4</u>**. Awon orile-ede ti nbowo fun ere ju Olorun lo, ni lati siwo ise-ibi yi lesekese, ki won si wo awon ere na pale. Awon orile-ede yi ma nwipe awon ere wonyi ni o nse afihan iru eya ti awon je, ni eyiti ki se otito, nitoripe esu nlo ategun awon ere wonyi lati si won lona, ati lati fi won sinu pakute pelu ajaga-ide. Awon orile-ede wonyi ma nse oniruru ayeye ati apejo pelu ajodun nitori awon ere-gbigbe won, dipo eyiti o fi yeki won ma se ayeye ati ajo ododun awon Kristiani.

**<u>Won lero wipe ko leto lati mo Olorun tabi lati jewo re :</u>** Eko Bibeli Mimo so wipe "Fi gbogbo aiya re gbekele Oluwa; ma si se te si imo ara re. Mo o ni gbogbo ona re: on o si ma to ipa-ona re" **<u>Owe 3: 5-6</u>**. Idakeji ni ohun ti o nsele

ninu aiye loni, nitoripe awon orile-ede ko ro wipe o ye lati mo Olorun, besini won ri bi ifi-akoko-sofo lati wa Olorun, tabi lati mo o. Awon orile-ede miran tile lero wipe isiwere ni lati mo Olorun, toripe awon wonyi ko, lati ni iro Olorun ni imo won, nitorina, Olorun fi won fun iye rira, lati se awon ohun ti ko to: nwon kun fun aisododo gbogbo ati oniruru iwa buburu **Romu 1: 28-29**. Irufe awon orile-ede yi ma nlero wipe awon ko nilo Olorun, atipe gbogbo aseyori won sele nipase ogbon-ori won. Ohun ti o se koko si awon orile-ede yi ni, aseyori ati awon ohunti won ti gbese ninu imo-sayensi, imo-ogun-jija, imo ilera ati imo oro-aje.

**Alaisotito ati jegudu-jera:** Ninu opolopo orile-ede awon osise-oba ati awon asiwaju won dabi ikoko ti nsode, lati taje sile, lati pa okan run, lati jere aisoto **Esekiel 22: 27**. Iwa ibaje yi ti tankale si gbogbo ile-ise ijoba, debipe iwa jegudu-jera nfarahan gidigidi ninu aiye awon adajo/onidajo. Awon olori won je kiniun ti nke ramuramu; awon onidajo re ikoko asale ni nwon; nwon ko san egungun titi di owuro **Sefaniah 3: 3**.

**Itaje-sile:** Itaje-sile po lapoju ninu aiye, ni eyiti o lodi si Ife Olorun. Bibeli wipe "Egbe ni fun eniti o fi eje ko ilu, ti o si fi aisedede te ilu nla do" **Habakkuku 2: 12**. Sibe ojojumo ni nwon nta eje alaise sile nitori imo-tara-eni-nikan ati ifekufe okan nwon. Fun idi eyi ni Olorun fi pase wipe mase ta eje alaise sile ninu ile re, ti Oluwa Olorun re fi fun o ni ini, ki eje ki o ma ba wa li orun re **Deuteronomi 19: 10**. Bi o ko ba fe ki ebi-eje wa si ori orile-ede re, siwo lesekese awon iwa adigun-jale, agbani-pa, itaje-sile ikoko, pipa oselu elegbe-eni, ipaniyan nitori esin ati terorisii.

**Abetele, owo ele ati iloni lowo-gba:** Abetele ati iwa ibaje ti di baraku ni opolopo orile-ede agbaiye, sugbon Olorun lodi si iwa-ibi yi. A kowe re wipe "Ninu re ni nwon ti gba ebun lati ta eje sile: iwo ti gba eda ati ele, o si ti fi iwora jere lara awon aladugbo re, nipa ifi iloni lowo-gba; o si ti gbagbe mi , ni Oluwa, Olorun wi" **Esekiel 22: 12**. Mase fun enia ni abetele, mase gba abetele, Jeki iwa iloni lowo-gba, owo-ele ati eda dopin ni orile-ede re.

**Iwa aini iteriba ati iwa odale/agbehin-beboje:** Ni ode oni, ninu opo orile-ede, awon omode nwu iwa aito ati iwa ijora-eni-loju, nwon ko si ni iteriba si awon alagba. Awon iwa ki awon omode ma pe awon agbalagba ni oruko laisi ibowo, je ohun ti o nsele lapoju; ki awon odo ma ta'buku ba awon arugbo, tabi ki won ma huwa alaini-iteriba ati iwa asa si arugbo-ori; nitori ola, ipo ati owo ti won ni;

awon alaimokan enia si lero wipe asa-igbalode ni **Isaiah 3:5**
Iwa odale ati etan je isele ojojumo bi enipe iwa aigbodo-mase ni, ohun ti Bibeli wipe ohun ibanuje ni **Orin Dafidi 119: 158.** Awon enia ndale nwon si nfi etan ba aya/oko, ijoba ati awon ti won gbani-si-ise lo. Nitori idi eyi ni Iwe mimo se wipe awon woli re gberaga, nwon si je eletan enia: awon alufa re ti ba ibi mimo je: nwon ti ru ofin **Sefaniah 3:4.**

**Awon ohun irira:** Ninu aiye loni, orisirisi ohun irirra ni awon enia nse. Lara won ni ao menuba yi: Ki nwon ma ko ami tatuu tabi gere sisin, okunrin nba okunrin lo'po, obinrin nba obinrin lo'po, sise irun-ori ni ona aito, okunrin nwo aso obinrin, besini obinrin nwo aso okunrin, ara-bibo, piparada lati okunrin si obinrin, piparada lati obinrin si okunrin. Niwon igbati o je wipe gbogbo ohun irira ni aisododo, eyi tumo si wipe gbogbo awon iwa ti ati menuba yi je aisododo niwaju Olorun. Bibeli wipe "Nitori eyiyi ni Olorun se fi won fun ife iwakiwa: nitori awon obinrin won tile yi ilo eda pada si eyi ti o lodi si eda: gege be ni awon okunrin pelu, nwon a ma fi ilo obinrin nipa ti eda sile, nwon a ma ni ifekufe gbigbona si ara won; okunrin mba okunrin se eyi ti ko ye, nwon si nje ere isina won ninu ara won bi o ti ye si. **Romu 1: 26-27.** Awon orile-ede ni lati dekun gbogbo awon irira yi, ti won nse, ki akoko to koja lo.

**Alaigboran ati alagidi:** Opolopo enia ninu awon orile-ede ni won ki gboran si Olorun lenu, beni won ki isi tele oro re, tabi mu oro re e se. Nwon ko gba ohun Oluwa Olorun gbo, beni nwon ko gba eko: otito segbe, a si ke e kuro li enu won **Jeremiah 7:28.** Opo orile-ede ni ki fetisi ohun Olorun; beni won ko gba eko; won ko gbekele Oluwa sugbon won gbekele ohun asan aiye; besini won ko sunmo odo Olorun **Sefaniah 3:2.** Opolopo orile-ede ni won ni igbagbo ninu oro-aje nla/gbigboro won, ati agbara ogun-jija won, ju ninu Olorun lo. Awon orile-ede wonyi ni lati yipada ni kiakia.

**Iwa eeri ati iborisa:** Opo orile-ede ni won mo riri awon orisa won; ti won si ngbe won ga ju Olorun lo, eyi si nfa iponju ati isoro ba won. Awon orile-ede wonyi ni lati gbagbo, ki won si mo wipe Oluwa Olorun wa, Oluwa kan ni. On ni Eleda orun ati aiye pelu ohun gbogbo ti mbe ninu re **Deuteronomi 6: 4**. Awon orile-ede ko gbodo ya orisa, beni won ko gbodo gbe ere tabi owon kan dide naro fun ara won, beni won ko gbodo gbe ere okuta gbigbe kale ni ile won, lati teriba fun u: **Lefitiku 26: 1**. Nitori idi eyi ni Olorun se fi won sile ninu ifekufe okan won si iwa-eeri lati se aibowo fun ara won: awon eniti o nyi otito Olorun pada si eke, **nwon si nbo o, besini nwon nsin eda ju Eleda lo,** eniti ise

olubukun titi lai. Amin **Romu 1: 24-25**.

**Inilara ati ole jija:** Awon enia opolopo orile-ede ni nwon nlo iwa-ininilara, nwon si nja ole, nwon si ti bi awon talaka ati alaini ninu: nitoto nwon ti ni alejo lara lainidi **Esekieli 22: 29**. Iru awon orile-ede be, ko gbodo gbekele inilara, won ko gbodo fi okan si iwa iloni lowo-gba, besini ko gbodo gberaga ni ole jija: bi oro won ba npo si i, won ko gbodo gbe okan won le e **Orin Dafidi 62: 10**. Egbe ni fun orile-ede eje ni! Gbogbo re kun fun eke, ati ole, ije ko kuro; **Nahumu 3: 1**.

**Isote ati aimo:** "Egbe ni fun awon olote omo ni Oluwa wi, ti nwon gba imo, sugbon ki ise ati odo mi; ti nwon si mule, sugbon ki ise nipa Emi mi, ki nwon ba le fi ese kun ese:" **Isaiah 30: 1**. Egbe ni fun olote ati alaimo orile-ede, fun orile-ede aninilara ni **Sefaniah 3: 1**. Awon orile-ede ni lati yipada kuro ninu awon aisododo won, ki won ronupiwada, ki won si yipada si Olorun ni kikun; ki idajo to de.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kejo: Osu keji Ojo kokandinlogun, 2017**

**Akori oro: Aisododo**……Apa kerin

**Eko kika: Romu 1: 18-32**

**Aisododo**

Abala ti o pari eko yi, yio tesiwaju nigbati ao soro nipa iyorisi aisododo.

**Awon iyorisi aisododo**

Opolopo ni awon iyorisi aisododo ti o wa ninu Bibeli, ao si soro die ninu won.

**Gbogbo aisododo ni ese:** Gbogbo iwa aisododo ni ese, ohunkohun ti o je aito, ti enia ba se ese ni, eyiti o tumo si wipe oniruru iwa buburu ti enia nhu ese ni. Lotito aisododo enia le ma jasi iku, ti iru eni be ba tete ronupiwada, ki akoko ironupiwada to koja lo **1 Johannu 5: 17**. Nitorina, yipada, ki o si jewo ese re; oloto ati olododo ni Olorun lati dari ese re ji o, ati lati we o nu kuro ninu aisododo gbogbo. Ranti wipe Jesu Kristi ko wa lati pe awon olododo, bikose awon elese si ironupiwada, eyiti iwo je okan lara nwon **Luku 5: 32**. Bi o ba yipada ni kikun si Olorun , igbana ni yio ko o ni ona re, yio si mu igbagbo re pada-bosipo; nitoripe rere ati diduro-sinsin ni Oluwa **Orin Dafidi 25: 8**.

**Awon alaisododo enia ti sina:** Gbogbo alaisododo enia ati awon ti won ni ife ere aisododo ti kuna, won si ti sako kuro ni oju-ona ododo ti o lo si ibi iye. Nitorina, mase ko ona otito sile nipa titele ona Balaamu eniti o feran ere aisododo **2 Peteru 2:15.** Mase jeki ife owo tabi ipo tabi okiki jeki o sako kuro ni ona igbagbo ati otito, nipa titele isise awon enia buburu ninu aiye **1 Timoteu 6: 10**.

**Irira ni si Olorun:** Gbogbo enia ti nyani-je ati awon alaisoto enia pelu awon alaisododo, irira ni won je si Olorun **Deuteronomi 25: 16**. Opo Kristiani ni won nse awon ohun irira ninu awon ile-ijosin. Nwon ngbe awon ohun irira ti inu Olorun ko dun si kale ni ile-Oluwa, lati so o di aimo **Jeremiah 32: 34**. Gbogbo iwa buburu yi ni lati dopin. Nwon ni lati mu awon irira kuro niwaju Oluwa, ki won si kuro ninu sise ohun irira, igbana ni won ki yio yese; nwon ki yio si sina tabi sako kuro niwaju Olorun mo **Jeremiah 4: 1**.

## Idajo

Ao so die ninu awon idajo ti o mbo si ori awon alaisododo enia.

**Ibanuje ati Ipayin-keke:** Ibanuje nduro de gbogbo enia ti won nse ofin-buburu ti won si npase-ika. "Egbe ni fun awon ti npase aisododo ati fun awon akowe ti nko iwe ika" **Isaiah 10: 1**. "Egbe ni fun eniti o ko ile re, ti ki se nipa ododo, ati iyewu re, ti ki se nipa eto: ti o lo ise owo aladugbo re lofe, ti ko fi ere ise re fun u" **Jeremiah 22: 13**. Bi o ko ba fe Ibanuje ati ipayin-keke ninu aiye re, mase pase aisododo. Bi o ko ba fe di eni-egun mase yanni-je, tabi lonilowo-gba, tabi lo ipa lori awon enia lati ko ile/ile-ise re lofe; laifi ere ise won fun won.

**Idajo:** Ao se idajo awon enia ti won kun-dun ki won ma se ibi, dipo eyiti o fi yeki won ma se rere. Ao se idajo gbogbo awon ti ko gba otito gbo, sugbon ti nwon ni inu didun ninu aisododo ni Bibeli wi **2 Tessalonika 2: 12**.

**Ibinu Olorun:** "A fi ibinu Olorun han lati orun wa si gbogbo aiwa-bi-Olorun ati aisododo enia, awon eniti o fi aisododo te otito mole" **Romu 1: 18**. Bi o ko ba fe ki ibinu Olorun wa si ori re, dekun gbogbo aisododo re.

**Nwon ki yio jogun ijoba Olorun:** Eyin ko mo pe awon alaisoto ki yio jogun ijoba Olorun? Ki a ma tan nyin je: ki ise awon ti nba ara won je nipa ibalopo, tabi awon aborisa, tabi awon ole, tabi awon omuti, tabi awon elegan, tabi awon alonilowo-gba ni yio jogun ijoba Olorun **1 Korinti 6: 9-10**.

## Awon ona lati bori aisododo

Awon koko-oro ti ao menuba yi je lara awon ona ti enia fi le bori aisododo.

**Ma wa ogo Olorun nigbagbogbo:** Mase wa ogo ti ara re, sugbon wa ogo Olorun ki o ba le bori aisododo. Ohunkohun ti o ba nse, se e fun ogo Olorun. Ipokipo ti o ba ba ara re, fi ogo fun Olorun. Ohunkohun ti o ba di ninu aiye, mase wipe nitori ogbon tabi imo tabi akitiyan tabi laala tabi iwe-kika re ni o mu o de ipo na, sugbon fi ogo fun Olorun ti o mu ki o se-se. Enikeni ti o nsoro nipa ara re nwa ogo ara re ati titobi-nla, ni eyiti o nsele lapoju ninu aiye loni. Idi eyi ni Jesu fi wipe"Eniti nso ti ara re nwa ogo ara re: sugbon eniti nwa ogo eniti o ran a, on li olotito, ko si si aisododo ninu re" **Johannu 7: 18**. Jeki o di mimo fun araiye wipe ko si aisododo ninu re, nipa wiwa ogo Olorun ati fifi ogo fun Olorun ni gbogbo igba.

**<u>Mase gbe ara-ninu Oluwa losi ile ejo:</u>** Ko oju ija si idanwo ati gbe ara ninu Oluwa lo si ile-ejo lati jeki awon alaisododo enia ni ipa lori re ki won si da o l'ejo. O dara ki o gba iyanje, pelu idaniloju wipe Olorun yio gbesan re, ju ki o lo si ile ejo lo **<u>1 Korinti 6: 1</u>**. E yanju ohunkohun ti o ba sele ni pelepele pelu iberu Olorun ni aisi ojusaju. E yanju ohun gbogbo nipa eko ati ilana Bibeli, ki a le ka si ododo fun yin.

**<u>Enia buburu ni lati ko ona re sile:</u>** Awon enia buburu ni lati ko ona won sile, won gbodo le ero ati se buburu kuro ninu okan won, ki won si pa ibi re kuro ninu gbogbo ero won. Awon wonyi ni lati ronupiwada, ki won si yipada si Oluwa ti yio sanu fun won. Won ni lati yipada si Olorun ti yio dari ese jin won **<u>Isaiah 55: 7</u>**. Bi o ba fe bori aisododo, ronupiwada ki o si yipada ni kikun si Oluwa.
O ni lati ri ara re gegebi elese, niwon igbati o je wipe "Gbogbo enia li o sa ti se, ti nwon si kuna ogo Olorun" **<u>Romu 3: 23</u>**. Lehin ti o ba ti mo ara re ni elese, iwo yio jewo ese re beni iwo yio si bere fun idarijin ese. O ni lati fihan wipe, inu re baje nitori awon asise re, beni iwo yio se ipinnu lati ma pada sinu ese mo. Nigbana ni Olorun ti o je olotito ati olododo yio dari ese re jin, yio si we o nu kuro ninu aisododo gbogbo **<u>1 Johannu 1: 9</u>**.

**<u>Mase yonda eya-ara re fun ese:</u>** Mase jeki esu lo ikankan ninu awon eya ara re bi ohun elo lati sin ese. Fi ara re patapata fun Olorun, toripe o ti ku, sugbon a ji o dide pelu aiye otun. Nitorina, lo ara re bi ohun elo lati se ohun ti o to fun ogo Olorun. Paulu gba wa ni imoran nipa oro yi wipe "E mase jowo eya ara nyin lowo fun ese bi ohun elo aisododo; sugbon e jowo ara nyin lowo fun Olorun, bi alaye kuro ninu oku, ati awon eya ara nyin bi ohun elo ododo fun Olorun **<u>Romu 6: 13</u>**. Ri wipe o ko jowo oju re, tabi eti re, tabi owo re, tabi ese re ati okan re lati lo gegebi ohun elo aisododo.

Lakotan ti o ba fe ki Oluwa ka o si olododo enia, bere sini sike awon talaka, ki o masi se fi eto won dun won. A kowe re wipe " Olododo a ma ro oran talaka: sugbon enia buburu ko su si i lati ro o" **<u>Owe 29: 7</u>**.

**<u>Edidi: Jeremiah 22: 3-5:</u>** Bayi li Oluwa wi "Mu idajo ati ododo se, ki o si gba eniti a lo lowo gba kuro lowo aninilara, ki o mase fi agbara ati ika lo alejo, alainibaba ati opo, beni ki o mase ta eje alaise sile nihinyi. Nitori bi enyin ba se nkan yi nitoto, nigbana ni awon oba yio wole enu-bode ilu yi, ti nwon o joko lori ite Dafidi, ti yio gun ketekete ati esin, on, ati awon iranse re, ati enia re.

Sugbon bi enyin ki yio ba gbo oro wonyi, Emi fi emitikarami bura, li Oluwa wi, pe, ile yi yio di ahoro".